AWON OHUN PATAKI NINU IWE OSEYI
Ẹgbẹ Agbẹ ko jẹbi
Oju iwe 1
Okebode gbebun
Oju iwe 1
Fa Ọgbọn yọ
Oju iwe 2
Atunse Ilu
Oju iwe 2

# IRAHỌ ★ OBOKUN

Akọ [illegible]
Oju iwe5
[illegible]
Oju iwe 5
Gbọ bi wọn ti wi
Oju iwe 7
Red Cross
Oju iwe 8
Obokun High School
Oju iwe8

Vol 4 No 145 ILESHA MONDAY JULY 18 1955. IYE OWO: TORO

# AGBE OKEBODE GBA EBUN (OWA'S CUP NITORI IMURA SI ISE AGBE

## ẸJỌ OLURẸNI ATI ỌSỌBU BARBER PARI

Lati ọjọ kerindelogun oṣu kini (January) ọdun yi ni Olu. Abiye ti gba iwe Ikọsilẹ fun Ọkọ rẹ Ọgbẹni Ọṣọbu Barber. O si sanwo ugbọn Kotu ti wọn ti tori owori ko jẹki wọn ṣejọ.

Ni ọjọ karundogun oṣu (July) yi ni wọn ṣejọ wọn ni Kotu Lọkọlaya lẹhin oṣu keje. Idajọ kotu na nipe ki Olurẹmi lọ san owo Oji toripe o ti loyun oṣu mẹta.

Kotu lọkọlaya dajọ pe ki wọn mu owo Oji na wa si Kotu ni ọjọ kọkanlelogun oṣu yi, wọn ni bi ko baṣe bẹ awọn yio yọ owo oji ninu owo ife ti wọn ti san silẹ lati oṣu keje

## IJỌBA TI ILẸṢA BA ILU ṢE IPADE

Lati nkan bi ọsẹ mẹta sẹhin ni iwe ti dọwọ gbogbo ẹgbẹ ni ilu Ilẹṣa pe ki aṣoju wọn wa si ipade ni ọjọ Monde to kọja.

Ipade na kun pupọ, o si yọri si dada. Wọn se orisirisi alaye nipa eto ilẹ, wọn si ṣe alaye nipa owo omi ati owo ina ilentiriki. Wọn tun ṣe alaye nipa eto ilera.

Lẹhin ọpọlọpọ alaye ni ọpọlọpọ enia bere ọrọ, wọn si fun wọn ni idahun to tẹ ohikulukụ lọrun. Akọkun irohin na yio jade lọsẹ to mbọ.

## IYA JAMES ADEYẸMI DI OLOGBE

Ni ọjọ alamisi ti iṣe ọgbọnjọ oṣu kẹfa ọdun yi ni Ọgbẹni James Adeleyẹ ri wayu gba ni Eko wipe Iya rẹ jẹ alaisi ni Ilẹṣa.

Lẹsẹkẹsẹ ni o mura ti o si ba ọkọ ayọkẹlẹ de Ilẹṣa lati wa sin oku iya rẹ. Ni ọsan ọjọ keji ni wọn gbe oku lọsi ile ijọsin Ijọ Afrika ni Odo - Aragan, Ilẹṣa. Nibẹ ni Alufa ijọ ti ṣe isin ikẹhin fun iya na, Marian Ajayi.

Lẹhin isin yi ni ogunlọgọ awọn enia si i lọsi (Iboji) ni biti wọn ti da gbere ikẹhin fun u.

Alufa sọrọ pupọ nipa olo gbe na, bi o ti ṣe jẹ oniwa rere ati olufọkansin to, ati bi o ti ṣe fi iwa rere rẹ fa gbogbgo awọn ẹbi lọtun ati losi mọra.

Awọn ọmọ oloku, Ọgbẹni James Adeleyẹ ati arabinrin Bandele Ẹsan ati awọn ẹbi gbogbo nawo pupọ ni ọjọ isinku na. Wọn si fi ijo ati ilu yọri isinku na ni dede agogo mẹwa alẹ. Irohin ko to afojuba ni ẹyẹ isinku na



ỌGBẸNI A. O. WILLIAMS

A tiyọ alaye ti a rigbọ nipa eto iraja ẹgbẹ agbẹ lọsẹ to kọja kuro. A si tọrọ aforiji fun ailotitọ to wa ninu alaye na.

## AGBẸ OKEBODE GBẸBUN ỌWA.

Ni ọjọ kerinla oṣu yi Rẹsidẹnt Ọyọ, Ajẹlẹ Ilẹ Ijẹṣa, Alaga igbimọ ijọba Ijẹṣa ati akọwe agba ti ijọba Ijẹṣa lọ si Okebode lati lọ gbe ẹbun (Ọwa's Cup) ti Ọwa fi silẹ lati ma fun awọn agbẹ to mura sise lọdọdun fun wọn

Okebode lo gba ẹbun na lọdun to kọja, awọn lo tun gba lọdun yi. Oloye Agunlejika Keji, Lọja Okebode lo gba ẹbun imurasiṣẹ ju lọdun to kọja ati lọdun yi.

Irohin nipa bi wọn tiṣe ṣe ayẹyẹ gbigbe ẹbun na fun wọn yio jade ninu iwe wa lọsẹ to mbọ.

## ADEDEJI KỌMỌLAFẸ LU IYA RẸ
(Lati Ọwọ Toronto.)

Ni ọjọ kẹwa oṣu yi ni dede agogo mẹjọ ni mo nti ọgbọn Idio kọja lọ si Okeṣa, ni mo ngbọ ariwo pe "ma paku" ma paku. Bi mo ti garun wo ibẹ ni mo ri arakunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Adedeji Obi Kọmọlafẹ tio gbe iya rẹ lulẹ, tio gun le lori, tio si ngba ni ẹṣẹ. Awọn Ọgbẹni Yakubu Agbo, ati Karimu Ajao lo gbe Ọgbẹni na dide lori iya rẹ. Laipẹ ni Ọgbẹni Ammon debẹ, tio nbe arakunrin na pe kio dẹkun lati ma fi iya "jẹ iya rẹ. Ṣugbọn Ọgbẹni onija na doju ija kọ gbogbo wa! Nikẹhin iya na ti orukọ rẹ njẹ Dada salọ si ago ọlọpa ibilẹ, o fẹjọ sun pe ki wọn gba oun lọwọ ọmọ yi.

Kọburu Jacob Ojo paṣẹ wipe ki wọn lọ ma kru ọmọ bẹ wa. Ṣugbọn o sa ni alẹ ọjọ na. Arọ Monday ni wọn to ri mu wa si ago ọlọpa. Awọn ọlọpa wadi ọrọ tio dun tobẹ. Ṣugbọn ko ri ohun pataki sọ ni awọn ọlọpa pa paṣẹ fun pe ki o fi de iya na silẹ, kio lọ ma gbe ile baba rẹ. Ọgbẹni na si ti ko awọn ijawo ati ẹru rẹ lọ si ile Baba rẹ.



ỌGBẸNI M. D. ỌLỌWẸ

On ni Baba-ẹgbẹ fun apapọ Ẹgbẹ Agbẹ *Ilẹ Ijẹṣa*. A ti ripe ọrọ ẹdinwo Koko ki i ṣe ebi ẹgbẹ wọn. A tọrọ aforiji lọwọ ẹgbẹ na, a si yọ alaye ti a rigbọ nipa wọn kuro ninu akọle wa lọsẹ to kọja.

## (CO—OPERATIVE) ẸGBẸ AGBẸ KO JẸBI

Ninu iwe wa ọsẹ to kọja, a kọ akọle Olotu kan, lori iwadi ti a ṣe nipa rira ati tita koko, lẹhin igbati a ri bi awọn onisọwo koko lati Ipinlẹ miran ṣe nra koko ti Ilẹ Ijẹṣa lọ nibiti onisọwo Ẹgbẹ Agbẹ wa. O dun ni wipe akọle na fẹrẹ tumọ pe awọn alaṣẹ Ẹgbẹ na din owo koko ku.

Ko ri bẹ rara. Bi owo koko ti Ipinlẹ Ijẹṣa ba din si ti Ipinlẹ miran rara, ki i ṣe wipe awọn Ẹgbẹ na lo din, ki i ṣe pe ti wọn yatọ si ti awọn onisọwo yoku ni Ilẹ Ijẹṣa rara. Nitorina a ko fẹ ki ẹnyin ọkawe wa ni ero wipe nṣe ni awọn Ẹgbẹ na nraja lọdinwo gẹgẹbi aṣa, tabi pe nṣe ni alaṣẹ wọn npaṣẹ ẹdinwo fun iraja tiwọn. Bẹkọ rara.

Otitọ to wa nibẹ nipe awọn koni adaṣe iye kan fun iraja wọn, nipa bẹ wọn ko le, san le tabi din niye owo ti gbogbo onisọwo Ipinlẹ Ijẹṣa nra koko. Nitorina, a yọ (withdraw) gbogbo alaye ti wọn fun wa nipa iraja Ẹgbẹ na kuro ninu Akọle Olotu wa ti ọsẹ to kọja, a si fi eleyi kẹwọ lati tọrọ aforiji lọdọ Ẹgbẹ Agbẹ na ati awọn Alaṣẹ wọn nitori inira ti iwe na le ti ma ba wọn. OLOTU

# TENDER.

**Tenders are invited for the printing of the following Local Government Forms for the Ijesha Divisional Council.**

| No. | Particulars of Forms or Books. | Quantity Required. | |
|---|---|---|---|
| 1 | For 'E' Wine & Beer off Licence Books No. 801 — 1600 (100 Leaves each) | 8 | Books. |
| 2 | Dispensary (3d) Tickets (200 Leaves each) | 40 | Books. |
| 3 | Maternity (3d) Tickets (200 Leaves each) | 40 | Books. |
| 4 | Store Register Books (200 Leaves each) | 2 | Books. |
| 5 | Hearing notices H.N. 3 H.N. 4c (100 leaves each) | 500 | Leaves |
| 6 | Proofs of Service (Affidavit) | 100 | " |
| 7 | Criminal Statistics Form | 500 | " |
| 8 | General 50 | 200 | " |
| 9 | General 64 | 100 | " |
| 10 | General 65 | 100 | " |
| 11 | Native Court 6 | 500 | " |
| 12 | Returns of Corporal Punishment | 200 | " |
| 13 | Transfer Order Form | 500 | " |
| 14 | Interim Order Form | 100 | " |
| 15 | Endorsement Form | 600 | " |
| 16 | Oyo Provincial Local Govt. Police Case Files | 500 | Only |
| 17 | Oyo Provincial Local Govt Form A/29 | 1000 | " |
| 18 | Ijesha Divisional Council (Liquor Licensing) Bye-Laws, 1948. | 100 | Books |

2. Specimens of these forms are available in the Secretary's Office, Divisional Council, Ilesha between the hours of 8. 30 a. m. to 1. 30. p. m. on any week days from Monday-Fridays.

3. The Divisional Council is not bound to accept the lowest or any tender.

4. Tenders should be sealed in envelops marked "Tender for Local Government Forms" at the top of the envelopes.

5. Tender close at 10. 00 a.m. on Saturday, 23rd July, 1955.

**(Sgd.) M. A. Akinwumi,**
Secretary,
Ijesha Divisional Council.

## E KA NIPA IJOBA YIN

Wọn ni "bi egungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olu. kuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe orişirişi atunşe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin ojade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aşoju wa bi fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iyẹ na rọrun ni şişe

Ọna ti ẹ fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Asoju (Agent) ni ilu kọkan,

A fẹ aşoju si ni Ileşa.
A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe.
A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.

A fẹ ki awọn ti o niura tan lati ma ba wa şowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Nitorina a nfẹ aşoju ti yio ma fun wa ni irohin ati ti yio ma ta Irawọ Obokun ni awọn ilu wọnyi:- Ẹşa, Ibodi, Iperindo, Imẹsi Ile, Muroko, Itagun, Ipole, Igangan, Isẹ. Odo, Ilọba, Iwara, Erin Odo, Erin Oke, Ẹsa odo, New Ikeji, Old Ikeji, Isaobi, Ijẹbujeşa, Etiọni, Ilerin, Ifẹ, Ibadan, Ọffa, Ikirun, Iragbiji.

# IROHIN LATI AGBEGBE

IPETU-IBOKUN

### AWỌN OKUNBANJỌ KO ỌMỌ TITUN JADE

Ni kutukutu owurọ ọjọ Isimi ni agogo meje abọ ni ni ojişẹ Ọlọrun ti Ipetu-Ibokun ati Apetu ati awọn Ijoye rẹ pẹlu awọn Ijọ Methodist wọle Ọdẹfin ana lati ko ọmọ ti Iya afin, Mary Adeọla Okubanjọ ti Iwo Station.

Baba ati iya ọmọ na si joko tẹyẹtẹyẹ pẹlu Apetu. Lẹhin igbati wọn şe isin igbagbọ tan Oloye Jacob Fatokun lo gbadura. Baba ọmọ na sọ ọmọ na ni Baba, na ni Adeyẹmi Babatude Oludamilare

Ọrọ ọjọ na titi di asalẹ miringindin tijẹ ati mimu su ọpọlpọ awọn ti o ti Imẹsi, Ibokun, Iwo Station ati Abẹokuta wa Iya Afin Comfort Ọlawumi Awoyinfa Iya, Iya ọmọ tuntun na, na wo pupọ nipa fifi onjẹ nti ọti mimu lẹ ọpọlọpọ lọrun titi fi di asalẹ, ọpọlọpọ ni ko mọ igbati ilẹ mọ.

Diẹ ninu awọn ti o wa ni Baba ọmọ ọmọ Ọba J. Ade Okubanjọ, A. M. Methodist Iwo Statoin, Iya ọmọ Mary Okubanjọ, Iya Iya Iya ọmọ Comfot Ọlawumi Awoyinfa, Mọmọdu Ọdẹwusi, Oloye Jacob Fatokun, Oloye Elijah (the Apetu of Ipetu Ibokun), S. B. Ajetunmọbi catechist Ipetu, Ọgbẹni Ajayi Sub Pastor Imẹsi Ọlọja oke, J. O. Ilọri H M Ipetu. Ibokun.

Ọmidan Alice Yẹmi Gbẹjẹ, Nurse Ipetu Ibokun Israel Olumọ, Samuel Adetoyinbo Ọdẹwusi; Ayẹni Deyi, Amos Ọdẹwusi; Enoch Ọdẹwusi, Joon Akanbi Wẹrẹ, Rasaki Salami, Noah Ọdẹwusi, Shitu Afọlab Fijabi Balẹ Ọyọ, Yeyelori Ọdẹwu i, Ojuọla Yeyeore Oni Aro Idi Obokun ti Ibokun ti Ibokun ati Lydia Faunmikẹ.

IPETU IBOKUN

### METHODIST CHURCH YA DURU SI MIMỌ

Ni ọjọ isimi ni irọlẹ, irọkẹkẹ lati ya duru ti awọn ijọ eleto ra si mimọ, tan ka Ipetu Ibokun. Irọkẹkẹ yi ti bẹrẹ lati ọjọ Satide, ti awọn ọmọ ile ẹkọ ati ọga ile ẹkọ, Ọgbẹni J. O. Ilọri gbe ilu ti wọn njo ti wọn nyọ ti wọn njẹ ti wọn si nmu tobẹ ti awọn ijọ tọkunrin tobinrin ko mọ igbati wọn bẹrẹsi jo yi ilu ka. Ojo nrọ şugbọn igbadun jijẹ ati mimu ko jẹki wọn mọ rara.

Ni ọjọ ọsẹ gan ni Sub Pastor Ajayi lati Imẹsi Ọlọja-Oke wa ya duru si mimọ. O sọ ninu ọrọ iyanju bi David ti mọ gita tita dada tobẹ ti Saul ọba paşẹ pe ko ma ta fun on ati bo ti jẹ wipe gbogbo enia ati ẹranko, ejo, ẹiyẹ lo gbadun duru lati fi ma kọrin; ati bi o tişe anfani fun ijọ yi pe wọn ni atọna orin lati ọjọ na lọ.

O gba wọn ni iyanju ki wọn maşe jẹki o rẹ wọn lati ma şe ohun rere fun ile Ọlọrun. O ranti awọn enia ti o ti ku ti wọn si lowo sinu idawo lati ra duru na, o si gbadura fun wọn.

J. Ade Okubanjọ lo ka ẹkọ keji, J. O. Ilọri si ka ẹkọ kini, Catechist S. B. Ajetunmọbi si ka awọn adura.

Olori awọn oluko, ọgbẹni Okubanjọ si tun gbani ni yanju ni isin alẹ eyiti o larinrin pupọ fun ẹmi, Ẹ sọ fun olododo wipe yio dara fun nitoriti yio jẹ işẹ ọwọ rẹ (Isaiah, 3: 10).

Sub Pastor Ajayi kọkọ fi Ibukun şi H. M. J. Ade Okubanjọ si fi Ibukun şi pẹlu. Owo ọpẹ ọjọ na jẹ £14: 13. 6. Owo ti wọn fi ra duru na jẹ £150.

### IKEJI KINI KEJI GBA BỌLU PỌ

Ni ọgbọnjọ oşu to kọja ni ọmọ ile iwe Ikeji titun lọ ba ọmọ ile iwe Ikeji jalilal gba bọlu Ere na sini lori tobẹ ti ọpọkpọ ara ilu wa lati wo wọn.

O si ni idanilọja pe ti eleyi ba le malọ dede ifẹ ati irẹpọ yio wà larin ilu mejeji.

A dupẹ lọwọ Ọgbẹni H. A. Oyebimiga ati Ọgbẹni M. A. Olowẹ fun gbogbo eto ti wọn şe ọjọ na.

## ỌRỌ LORI KOKO ỌDUN YI
(Lati Ọwọ Joshua Ọṣẹwa, Oke – Ọṣin)

Olotu jọwọ gba mi laye lati sọ ẹdun ọkan mi yi ni tori koko ti ọdun yi.

A wa ngbọ finrinfinrin wi pe koko yio gewo ninu ọdun yi. (1955–56).

A bẹ awọn onisọkusọ ti o sọ wipe koko yio gewo lati pa ẹnu wọn mọ. Nitoripe bi ojo ko ba rọ ti igbado ko gbo, oju takọ tabo ni yio ja.

Ti koko ba lọ gewo pẹ ẹ ni ọdun yi, oju gbogbo wa ni yio ja o. Nitoripe nitori koko yi ni awa agbẹ ṣe gba ogun ati ẹrọ kori-kori lawin lọwọ ijọba, a si ni ipinnu lati san owo rẹ ni ipayi ọdun yi gẹgẹ bi ijọba ti wi.

Njẹ bi koko ba lọ gewowa gba ọran yi ro o. bawo ni a o ti ṣe le san owo na fun ijọba ti ko ni fi di igbese si wa lọrun?

Nitorina mo fẹ sọ fun gbogbo ẹnyin ara mi wipe bi iṣẹ agbẹ ko ba ni ilọsiwaju gbogbo iṣẹ ni yio fa sẹhin patapata. Ẹ jẹ ki a fi ti ọdun yi ṣe akawe; njẹ ẹ le mọ wipe aisi koko lọdun yi lo fa aisowo lọwọ gbogbo wa ati ilẹ wa pẹlu?

Ọdun kẹrin ti awa Ẹgbẹ Agbẹ (Nigirian Farmers Union) ti nṣe rogbodiyan wipe ki koko wa di £12 fun okuta kan ,niyi lati igbana ọwọ wa koiti ba £11 Nitorina ti ko ba lọ si iwaju kotun yẹ ki o lọ sẹhin mọ o.

Nitorina a fẹ ki ijọba ba

## ALAGBA JOEL OJO DI OLOGBE

Ni dede agogo mẹjọ abọ go mẹrin abọ irọlẹ ni awọn oru ọjọ Monday ti i ṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni okiki kan ni adugbo Oke-Ẹṣọ pe Alagba Joel Ojo di ologbe.

Alagba na jẹ ẹnikan pataki ti o nsin Ọlọrun, o si jẹ ọkan ninu awọn olujọsin ni Ijọ Ilọrọ Ilesa.

Iku rẹ jẹ ẹdun ọkan fun ọpọlọpọ enia nitoripe Alagba na jẹ onisuru ati enia jẹjẹ nigba aiye rẹ.

Nigbati o di ọjọ keji ti i ṣe ọjọ Tuesday ni dede ago awọn ara ile, ẹbi, iyawo ati awọn abanikẹdun mura ti wọn gbe oku rẹ lọ si iboji. Nigbati Alufa ṣe iwasu tan ti wọn si pari isin isinku ni wọn bẹ rẹ inawo nipa pipese jijẹ ati mimu fun ogunlọgọ enia.

Diẹ ninu awọn ẹniti o wa sibi isinku alagba yi ni awọn Ọgbẹni:- O. Adeyokunnu, M. O. James, Joseph Olowokere, J. O. Dagunduro, Ọdanye, J. O: Awosan ati awọn ọpọlọpọ enia.

## A FẸ IKORITA IWỌN KOKO (CRADING STATION)
(Lati Ọwọ D. A, Kabara, BII 7, Odo Iro)

Si Olotu Irawọ Obokun, Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi la e lati ba yin ṣe aṣaro diẹ ninu irohin yin oloyin mọmọ ti ilẹ Ijẹṣa Obokun nipa iwọn ikorita (Grading Station) ibiti a ti ma ngiredi koko ni Ilesa.

Ekini nipa ọrọ mi nipe, ninu ọdun to koja yi gbogbo wa gbọ wipe iye ton cocoa (koko) tiwọn giredi ni Ile-ifẹ lọpo (double) iye ton koko tiwọn giredi ni ilẹ Ijẹṣa lọna meji tabi jubẹlọ.

Ero wa ni pe ko yẹ ki Ile-ifẹ giredi ju wa lọ tobẹ. Ṣugbọn o yẹ ki a tun ronu lori ọrọ yẹn lọpọlọpọ, ati awọn ọlọla wa.

Ekeji nipe Igberiko ti awọn ti ma giredi koko ni Ile-Ifẹ fẹrẹ to mẹsan ti ko ba ni le ju bẹlọ gẹgẹbi mo ti gbọ. Njẹ ni ilẹ Ijẹṣa nkọ? Emi so wipe a le ti ilu mẹrin lẹhin Ilesa, ti awọn ti ngiredi koko. Beni ibi mẹsan ti mo tọka niti Ile-Ifẹ yi ko iti kan ọpọlọpọ ibiti awọn ti ma ngiredi laria igboro Ile-Ifẹ papa. Igberiko ti wọn ngiredi koko lẹhin ti Ilesa ti mo mọ ni Ibokun, Ipetu. ati Oṣu

Ẹkẹta nipe gbogbo koko t o. wa ni apa Itagunmodi, Ararọm, Iṣọtun, Ilọba, papa idaji koko to wa ni Ibodi, Ilo-fẹ niwọn ko lọ fun gigiredi, afi eyito bẹ jẹpe awọn ẹgbẹ agbẹ (Co-operative) lo gba nikan lo nlọ si Ilesa fun gigiredi.

Nitori idi eyi a bẹ ẹnyin Ọlọla wa, lati gba ọrọ yi yẹwo, ki ẹ si tun ronu ilu ti ẹ ba mọ wipe o yẹ ki a ti le ma giredi koko.

Papa awọn ilu pataki pataki gẹgẹbi Ijẹbu-Ijẹṣa, Iwara, Ilẹwara, Esa, Okebode, Itagunmodi ati Ibodi gbọdọ ma giredi ni ilu wọn.

Ẹ jọwọ ki ẹ gba ọrọ mi yẹwo o, ẹnyin ọlọla wa,

Ọrọ mi niyi o, ẹnyin Olotu Irawọ Obokun, ọkọ Ọba ko n ṣa yin lẹsẹ o, iwaju ni ọpa nre si o.

# AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ N.NC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.



ỌMỌBA O ADEYOKUNNU

On ni Olukọ Agba ni Ilewe Ọmọfẹ. On ni baba ẹgbẹ fun ẹgbẹ Akẹkọ (Students Union) ti Ilẹ Ijẹṣa. On na pẹlu ogunlọgọ awọn abanikẹdun to lọ si ibi isinku Alagba Joel Ojo.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

# GBỌ BI WỌN TI WI

## IJỌBA IJẸṢA GBIYANJU

(Lati Ọwọ Rufus. O B O. Abẹ, Ilẹṣa Gramma School)

A dupẹ lọpọlọpọ lọwọ Ijọba Ijẹṣa wipe wọn fun wa ni Gareji (Garage) titun ti a ti nbere fun Ilẹṣa fun ọpọlọpọ akoko!

Iranlọwọ pataki ni eyi jẹ fun Ilẹṣa nitoripe opopo ọja Ọba kuru ni fifun mọ nipa wipe moto ko ni jẹ ki a kọja ni opopo ọja ọba Ilẹṣa.

Ṣugbọn a ri pe a ni ibuso moto kan kekere; ṣugbọn sibẹsibẹ ko ti tobi to, nitoripe ko gba awọn moto tan. Nitori eyi o yẹ ki a tun bẹ Ijọba Ijẹṣa wipe ki wọn ba wa mura lati tun gareji to wa ni ọgbọn Idio ṣe dada nitori mo ri mọ wipe gareji ti ọgbọn Idio ti wọn ko iti tunṣe yẹn, yio tobi ju ti gareji idi okuta iranti Ogedengbe.

A dupẹ lọpọlọpọ nitoripe anfani pataki ni eyi, o si tun jẹ nkan ti o ba oju mu ni Ilẹṣa.

Mo dupẹ lọpọlọpọ lọwọ Alagba Alaga ati oṣiṣẹ Irawọ - Obokun, fun aye ti ẹ fun mi lati sọ ọrọ mi yi jade. Obokun yio gbe yin o

Ọmọ yin kekere ni o ki yin o.

---

## Ẹ F'OYE SAWẸ SILẸ FỤMỌ SAWẸ

(Lati Ọwọ Jeje Sawẹ, E 87, Ijamọ St. Ilẹṣa)

Emi Jeje Sawẹ jẹ ọkan pataki ninu awọn to pataki to si jẹ oju lowo ọmọ Sawẹ ni Ilẹṣa. Lati ọjọ ti alaiye ti daiye, ti Baba nla wa ti bi awọn ọmọ rẹ to njẹ Sawẹ, a ko i ti gbọ ri ninu itan, bẹni a ko i ti ri ri pe wọn jẹ oye Sawẹ lati idile miran ni Ijamọ.

Ṣugbọn o yami lẹnu pe awọn kan nfi igba to di igba oyinbo kẹwọ, wọn si nfẹ lati ma foju egbo tẹlẹ. Bẹni o jẹ ohun to sewọ pe ki a ka eto awusa si ori igi obi. Nitorina kini ṣe ti ẹnyin ti oye Sawẹ ko tọ si ndu oye Sawẹ, nigbati o jẹ pe ẹ mọ pe ẹ ko dide nidi iran Sawẹ?

Mo fi eleyi kẹwọ lati bẹ ẹnyin ti oye ko tọsi ti ẹ ndu oye oloye pe ki ẹ ti mọ nibiti ẹ de yẹn o, bi bẹkọ ẹ o ba iṣu nidi ewura; ẹ si ba owu dudu nibiti ẹ ti lero lati ri funfun o.

Ẹnikẹni to ba wu lati joye ni anfani lati jẹ ninu awọn oye ti awọn Baba nla gbogbo awa Ijẹṣa ti pese silẹ lati ma fida awọn Ijẹṣa to ṣiṣẹ rere fun orilẹ-ede wọn lọla. Ẹniti oye ba wu ko ṣiṣẹ fun itẹsiwaju ati igbega Ilẹ Ijẹṣa kia ni Ijẹṣa yio fi oye da lọla.

Nṣe ni ọrọ mi ṣẹṣẹ bẹrẹ lori awọn ti ki i ṣe ọmọ oloye ti wọn si ndu oye mọ awọn ọmọ oloye lọwọ.

---

## ADIẸ BA LOKUN

(Lati Ọwọ J. O. Daradedi, Ẹde)

Mo ki ọmọkekere ilu ati agbagba, mo si ki Ọba ati awọn ijoye rẹ pe wọn ku adimu iiu. Oluwa a jẹ ki ẹ ṣe pẹ o. Ẹ si ku amojuba rogbodiyan, rogbodiyan ni arin ilu.

Ni ojojumọ ni oju mi ma nri orişirişi nkan ti eti mi si ngbọ orişiri ọrọ. Ọlọpa inu pọ lori oko gẹgẹ bi ẹru. Bi wọn ti nbẹ loko ni wọn wa larin ilu ti gbogbo wọn nsun ahere oko kiri loriko; ati obinrin ati ọkunrin ni nṣe ọlọpa inu kiri.

Ọrọ na kamọmọ. Nitori kini awọn enia wọnyi nkiri si o?

Ara ilu ẹ kiyesara ki ẹ si mojuto oriko yin ki ẹ si mojuto arin ọja yin ni ọjọ ọja yin. Edumare a ba wa tun ilu wa ṣe o.

Ẹ o tun ma ri ọwọ mi nigbamiran.

---

## AWỌN AGBERO OṢOGBO ATI ILEṢA

(Lati Ọwọ Ọgbẹni A. K. Aojọrin, 102 Station Rd. Oṣogbo)

Mo tọrọ gafara, kẹ gba mi laye diẹ ninu iwe yin aladun ati oloyinmọmọ yi. Ẹ jọwọ alaye diẹ ni mo fẹ ṣe nipa awọn agbero ilu Oṣogbo ti wọn ma npolowo moto fun ero ni Oṣogbo. Ipolowo na ko tẹ awa ọpọlọpọ Ijẹṣa lọrun. Awọn abanirọnu tabi abanigbero na a ma kepe ero bayi pe "Ilẹṣa, Ilẹṣa Ilẹṣa, Ilu oṣomala, Ilẹṣa ilu muke, Ilẹṣa ilu alagidi".

Njẹ awọn wọnyi nba Ilẹṣa jẹ ni tabi wọn ntabuku Ijẹṣa ni tabi wọn nṣe apọnle Ijẹṣa? Alagidi lo tẹ Ilẹṣa do ni tabi awa ọmọ Ijẹṣa nia nhuwa Ọlẹdarun ni tabi owo muke nikan ni a ma nṣe nigboro Ilẹṣa?

Mo fi Ọla Ọlọrun ati alafia pẹlu iṣọkanbalẹ ilu bẹ awọn to ba nfẹ irẹpọ larin Oṣogbo ati Ilẹṣa lati kilọ fun awọn agbero na. Mo bẹ awọn ọga onimoto lati kilọ fun awọn Dirẹba wọn ki wọn ma ba orukọ Ilẹṣa wa jẹ mọ nipa fifi ilu dara dara we ohun ti ko dara. Ki ṣe gbogbo Dirẹba ni mo nba wi o, awọn diẹ lati Oṣogbo si Ilẹṣa ati Ilẹṣa si Oṣogbo ni o.

Oṣogbo nibi ni awọn Agbero na ti ma nda aṣa na; bọya wọn nṣe bẹ ni ilu miran emi ko mọ o

AKỌLE OLOTU:- A bẹ ẹnyin agbero ati awamoto Ilẹṣa ki ẹnyin na ba ni kilọ fun awọn onimoto to nwa lati Oṣogbo pe Ijẹṣa ko faramọ eto ti wọn fi npolowo Igbero wọn ni Oṣogbo o. Ti wọn ko ba dawọ iṣọkuṣọ na duro a bẹ ẹnyin ti ẹ ko ba faramọ lati fọrọ ena le [illegible] ki ẹ si ma wo

---



AGUNLEJIKA KEJI, LỌJA OKEBODE

On ni Alaga fun Ijọba Akamọ Okebode. Awọn ara Okebode lo gba ẹbun Ọwa lọdun yi lori imura wọn si iṣẹ agbẹ. Lọja na funra rẹ gba ọpọlọpọ ẹbun,

---

## E FI IROHIN IPADE IGBIMO YIN

SỌWỌ FUN TITẸ JADE NINU

# Irawo Obokun

---

## IKEDE IPADE IDILE OGBONI

Ipade pataki kan wa fun gbogbo ọmọ Idile Oye Ogboni Ilẹṣa ni ọjọ keri lelogun osu yi (24/7/55). Ile Olodu ni ao ti ṣe ipade yi ni Ile Oye Ogboni Ilẹṣa.

Ninu Iran tabi idile Ogboni, a fẹ ki Iran kọkan yan enia meji ti o mọ itan Iran wọn wa si Ipade yi fun aṣoju Iran tabi Idile wọn. Enia meji meji fun Iran kọka ni ki o wa. Ọrọ ti a fẹ sọ ni ipade yi, jẹ ọrọ ti o kan gbogbo Iran ti ṣe ti Idile Oye Ogboni, fun eto titun ti o fẹ jade nipa ọrọ lori Oye Idile tabi Oye Iran.

Ki ẹnikẹni ma ba sọ pe on ko gbọ nigbati ẹnifẹ eto bayi ṣẹlẹ ni a ṣe ṣe ikede ọrọ yi si 'eti gbọ gbogbo ọmọ Ogboni. Iran tabi Idile ti ko ba wa, ki ṣe ebi ẹnikan, ebi ọwọ ara wọn ni o. Agogo meji ọsan ni a fẹ bẹrẹ ipade na ni ọjọ na. Ki oṣẹ gbogbo awọn Aṣoju yi ki o pe ki o to di agogo meji na. Ẹ jọwọ, ẹ maṣe pẹ fun akoko yi o. Agogo meji ọsan ni ipade Oṣẹ aro ni o.

OLODU A GBE NYIN O.

**J. O. Layide**

Nipa aṣẹ gbogbo Idile Oye Ogboni Ilẹṣa.

---

## IFILỌ PATAKI

### Fun Awọn Onibara Wa

A bẹ olukuluku awọn Onibara wa ti wọn jẹ IJESHA PRESS ni igbese ki wọn ki o mu ni ọkunkundun lati jẹki igbese ti wọn jẹ ki o tete de ọwọ Olotu Iṣẹ yi ni ipari oṣu June titi di ipari ọsẹ kini ninu oṣu July 1955, ki a ba le ni igbende nla ninu apakan iṣẹ yi ti o ti ku;

